28 FEB 1966


# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE TENI : GBOGBO LAWA

NO 1,670 THURSDAY FEBRUARY 17, 1966 (2D)


## Awon Kan Dana Sun Olopa !

SANTO-DOMINGO:- Ọrọ di pẹentuka, gboabo enia si bẹrẹsi sare ọlọmọgbọpon nigbati rogbodiyan nla kan bẹsilẹ larin awọn ọmọ ile iwe Unifasiti ilu Santo Domingo ti awọn ọlọpa si yinbọn pa awọn ọmọ ile ẹkọ mẹta na, ṣugbọn ọkan ninu awọn enia na sa ina si aṣọ ọlọpa na laye ni opin ọsẹ ti o kọja lọ yi.

Irohin awọn ọlọpa ilu Santo-Domingo fi ye wa pe awọn ọmọ ile iwe inu ilu n ni nwọn bina da iṣẹ silẹ ti nwọn ko si ṣe iṣẹ wọn mọ ti gbogbo wọn si ile iwe wọn silẹ ti nwọn si nkiri kakiri nitoripe nwọn lodi si ọna ti awọn alaṣẹ ile ẹkọ na ngba kọ wọn ni ẹkọ.

Ṣugbọn nigbati awọn ọlọpa lọ da,wọn ọmọ ile ẹkọ na lẹkun ti nwọn ko si dekun, ni awọn ọlọpa ba yibọn pa mẹta ninu awọn ọmọ ile ẹkọ na, ṣugbọn nigbati ọwọ awọn ọmọ ile ẹkọ na tẹ ọlọpa kan nwọn lu ọlọpa na ni ilukulu to fi jẹ pe, Ọlọp na ko le dide nilẹ mọ.

Nibiti ọlọpa na ti ṣjoro nile ni ọkan ninu awọn ọmọ ile iwe ti o wa nibẹ ti

WO OJU EWE KẸFA

# IJỌBA BILẸ OGBOMỌSỌ JẸ GBESE ỌKẸ-META PỌNUN

OGBOMỌSHỌ:— Gbogbo ile lo kun ṣọṣọ ti ọsẹ ko si gba ero fun ogunlọgọ ọkẹalmọye awọn enia ti nwọn wa si ibi ti awọn alaṣẹ Ijọba Ibilẹ agbegbe ilu Ogbomọsho ṣe ipade ninu Gbọgan inu ilu na ni opin ọsẹ ti o kọja lọ yi.

Oniwe Irohin wa ni Ogbomọshọ fi ye wa wipe, ni deede agogo marun irọlẹ ni ọsẹ gbogbo awọn Ọba, Ijoye, akọwe ile iṣẹ Ijọba ati gbogbo a w ọ n enia saraki saraki yika gbogbo ilu na ti parọjọ ti nwọn si nduro de akowe Ijọba Ibilẹ na.

Gbogbo awon enia ti nwon wa ninu ipade na ni nwon ya ẹnu sile ti nwon ko si le pade mo nigbati Ọgbẹni E. A. Oke akowo Ijoba Ibilẹ na nso fun gbogbo awon e n i a ti nwọn wa si ibi ipade ojo na wipe, Ijoba Ibile agbegbe ilu Ogbomosho ti jẹ gbese Ọkẹ mẹta o le ẹdẹgbajo Ọkẹ p ọ n u n [£75,000] nisisiyi.

Oniwe Irohin wa so wipe, bi Ọgbẹni Oke ti sọ oro yi ni gbogbo awọn Ọba, I j o y e ati gbogbo awọn akọwe ti nwọn wa ninu ipade na wo ara wọn loju, ṣugbon kosi ẹniti o soro ninu wọn.

Siwaju ninu ọrọ rẹ, Ọgbẹni Oke tun sọ wipe, gbese ti on sọ wipe Ijọba Ibilẹ agbegbe ilu Ogbomọshọ jẹ yi, Ijọba Afunshọ ilu Ogbomọsho eyiti Ijọba Olo'ọgun Orilẹ ede yi tuka lo jẹ gbese na.

Ọgbẹni Oke tun sọ siwaju ninu ọrọ rẹ fun awọn ọmọ ile Igbimọ na wipe gbese ti Ijọba na jẹ yi jẹ owo ti nwọn fi ntun ilu Ogbomọshọ se ati owo oṣu ti Ijọba na nsan fun awọn oṣiṣẹ ile iṣẹ wọn ni oṣoṣu

Ni ipari ọrọ rẹ, Ọgbẹni Oke rọ gbogbo awọn Ọba ati Ijoye ti nwọn wa si ibi ipade na wipe, ki awọn enia na tete yara lo sọ fun awọn enia wọn lati tete san owo—ori ti ọdun ti a wa ninu rẹ yi, ki Ijọba le ba ri owo lo lati ṣe gbogbo iṣẹ ti o wa niwaju wọn ninu ọdun yi.

Ṣugbọn Ọgbẹni Oke ko sọ ninu ipade na fun gbogbo awọn ọmọ Ile Igbimọ na bi Ijọba lọ ya owo na ni tabi nwọn lọ gba ni ọdọ awọn enia kan tabi nwọn ya owo na ni Banki

Ọkan ninu awọn enia na ti nwọn jẹ ọmọ Ile Igbimọ na sọ fun Oniwe Irohin wa wipe, bi ko ba si Ijọba Olo gun ti o gba Ijọba lọwọ awọn ọmọ ẹgbẹ Oṣelu ti nwọn ti nṣe Ijọba tẹlẹ ri,

WO OJU EWE KẸFA

# Iyawo Balewa Bi'mọ



Ologbe Alhaji Tafawa Balewa

BAUCHI:— Ninu Irohin kan to de ile iṣẹ wa lati ọwọ Oniwe Irohin wa ni ilu Bauchi Ipinlẹ Ariwa ilẹ Naijiria ti iṣe ile Ologbe Alhaji Abubakar Tafawa Balewa Alakoso Apapọ tẹlẹ ri ni a gbọ wipe Ologbe Alhaji Abubakar Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria tẹlẹ ati igbakeji Olori ẹgbẹ Olomi (NPC) bi ọmọ binrin titun jojolo kan ninu ọsẹ to kọja lọ yi.

Irohin na tun fi ye wa pe ọkan ninu iyawo Ologbe Alhaji Abubakar Tafawa Balewa Malama Jumai lo bi ọ Obinrin jojolo na ni ọsẹ to kọja lọ yi. Ninu irohin lati ọwọ Oniwe Irohin wa ni o ti ṣe alaye pe ninu ile iyawo Ologbe Abubakar ni adugbo kan ti nwọn npe ni Kan Street, Bauchi ni iyawo Ologbe na bimọ si

Oniwe Irohin wa tun ṣe alaye ninu irohin rẹ pe ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu yi ni nwọn ṣe ayẹyẹ ikomọ jade ọmọ Ologbe Alhaji Abubakar na ati pe nwọn si ṣe ayẹyẹ isọmọ titun na lorukọ ni ilana ẹsin Islam eyiti nwọn sọ ọmọ

WO OJU EWE KẸFA

# ALADINI TI ṢE ỌMỌ IBRAHIM

Nigbato de'e Ilu nda gbogbo enia bẹrẹsi jo, nigbati o to asiko ti wọn ni lati gbe iyawo lọ si ilẹ Ọkọ re, Aladini ba atupa rẹ, Alujannu meji won yẹn tun jade, wọn ni ki ni o fẹ ki awa ki o ṣe fun ọ, ẹniti o bẹ ni iru atupa yi ja nṣe nkan fun.

Oni ile on, bedi ti ko si iru rẹ ni Ilu yi, ti ko si ni Ile Ọba, ge yara ko si yara to wa ninu ile on yi, ki elo gbe Badru bade, wa si ori bedi ki on Ọba nibẹ.

Ki o to wibẹ tan gbogbo ohunti o wi ti de, o ti lọ ba Badru bado, Ọba lo pe, won bẹrẹsi ni ṣere.

Nigbati wọn wa Badru dado ninu ile ti wọn kori, gbogbo ilu daru, wọn ko nba on ti wọn lẹsẹ, larin agogo mẹrin idaji ọjọ keji o tun de Badru bado pada si inu ilu wọn.

Nigbati wọn ṣe ilẹkun, wọn ri ninu yera, nwọn bere lọwọ rẹ wipe nibo lo lọ,? O nigbation nma ba ara oni ile Aladini ea ba ara on, wọn ni ṣe ibẹ lo nsun on bẹni.

Nwọn ba mu losi Ile ọkorẹ Ọmọ igbakeji Ọba ni oke rẹ, Ọba ni on ti on lọ niyi o, o ti di abemi a se eniti o kọ ile ki ile to mọ. Wọn mu Badrubado lọ si ile oko rẹ,

Wọn ko a yika tun wa fi nile nigbati o.o agogo mẹ wa alẹ ti nwọn sun Aladini ti tun da pada wa si ile rẹ Won wa ranṣẹ si pe wa ni gbana o de won sorọ fun.

pe awọn ylo fi silẹ fun.

Nigbati yio fi to ọlọ mẹlo kan, babalawo ọjọ si, ogbe ifẹ rẹ o da wadi ọmọ ti o fi sinu ile ifa sọ fun pe ọmọ na ko ku, o njaiye ti rẹ ni oni bawo ni on sẹlẹ ri ọmọ na ki o si gbe atu pa na,

Ifa na si dahun wipe ati to ba lọ ro atupa tuntun ka yọ Ka ma lọ si onsirisi Ilu, ki o ma kigba bayi pe tani atupa aloku ko wa gbọ tuntun,

Ni o ba gba bẹ o si bere ni kiri ka bi oti nkiri lọ o wa kan Ile Aladini ko si Aladini nibẹ Iyawo rẹ wa yọju loke, ori dbẹni yi oni awọn atupa aloku.

A bi were ni ni o ba wore, o gbe otupa yi fun baba lawo yi ọgba tuntun ẹ ọkunrin yi wa tesi rẹ won fi okuta na awọn Alujannu keni jadesi wọn bẹ lere wipe, kini o fẹ ki awa ko se fun o n tori eniti o ba ti ni atupa yi lọwọ ni a nṣe nkan tun.

Oni on o fẹ ara on ni ilu on nisisiyi ko to sọ bẹ tan oti de ile rẹ babalawo to de ile ha atupa yi, wọn tun si gẹgẹbi iṣẹ wọn. Wọn si bi lere on to lẹ.

Oni on nfẹ ara on ni ile Aladini bado ti Aladini ba wa nile, ko yo sile ko to sọ bayi tan o ti ri bẹ. Aladini wo fẹrẹ, o ya lẹnu.

Nigbati awọn aṣọ fofo ripe awọn ko ri ile Aladini mọ, wọn lọ ṣofofo fun Ọba pe awọn ko ma ri ile Aladini mọ. Wọn o si tun ri Badru bado Ni Ọba ba ranṣẹ si Aladini pe Ọmọ on da. Aladini ko le sọrọ.

Ni igbakeji Ọba wa sọ wipe, awọn ko ti sọ fun wọn wipe Oni da jo lẹ fẹ Ọmọ yi. Ni wọn ba mu Aladini, wọn de, wọn fẹ pa, O si wa sọ fun wọn pe ki wọn ma pa on.

Oni ki wọn o fun on ni ọjọ mẹta ki ohun ti Oba ri ko ṣe fun on, Ọba si dahun wipe ko buru.

Aladini wa ranti Oruka ijosi ti o wa lọwọ rẹ. Oruka yẹn ko lagbara to atupa ṣugbọn o ni iṣẹ tirẹ. Wọn bere lọwọ rẹ wipe Nibo lo lọ ? O ni nigbati nma ba ara on, Ile Aladini non ba ara oi.

Iyoku di Ọla O.

# Ọmọ Ọlorun Ni Jesu

Mo ki Olotu iwe Irohin Imọlẹ bakanna ni mo tun ki awọn alabaṣiṣẹ pọ rẹ fun akitiyan ti awon nṣe nipa ariyanjiyan ti a ti nri ka ninu Irohin Imole lati ose diẹ sehin nipa pe Jesu ọmọ Ọlọrun ni iṣe ti awon enia kan tun nso pe Jesu ki ise ọmọ Ọlọrun

## Lati Owọ Emmanuel Alẹshinlọyẹ

Mo fe ki awon enia ti o je alatako si oro na lo mo daju pe ọmọ Ọlọrun ni Jesu Kristi ise nitoripe ninu gbogbo awon ojise Ọlorun ti o ti wa ki Jesu to de ko si eyiti nwon ko ba iya re sun, ṣugbọn ti Jesu Kristi ko ri be rara

Mo si fe ki o ye nyin daada pe ọmọ Ọlọrun ni Jesu jẹ leh nti Bibeli so tan Alukurani tun wa jeri si pe bẹẹni ọmọ Ọlọrun ni Jesu ise Mo fe tun pe akiyesi nyin sinu Bibeli nyin ki ẹ ṣi Mika ori karun ẹsẹ keji ibẹ ni nwon ti so pe "A ti mo Betlehemu Efrata bi iwo ti je kekere larin awon ẹgbẹgbẹruu—

Ti a ba ka ibiti mo yan yi daada ẹo ri wipe bibi ti a ma bi Jesu Kristi ni won so fun wa nibe Ẹnyin Onkawe mi ki nto pari oro mi ẹ wo Isaiah ori keji ese kerinla.

Nibe ni o ti so pe Oluwa tikalare yio fun nyin li ami kan, kiyesi Wundiya kan yio loyun, yio si bimo okunrin kan yio si pe oruko re ni Emmanuel, itumo eyiti ise Oluwa wa pelu wa nitorina mo fe ki e lo mo dajudaju pe Jesu Kristi ti ise Oluwa wa ọmọ Ọlọrun nise mo tun fe ki e lo mo wipe kise awa onigbagbo nikan ni anpe ni ọmọ Ọlọrun awon elemi eṣu paapa gba pe ọmọ Ọlọrun ni Jesu ise

Ẹnyin ara mi ninu Oluwa ẹ wo iwe mimo nyin ki e lo wo Matthew ori kini ese

Wo Oju Ewe Karun



Woli Kogberegbe

## IWE KOṢEMANI NI EYI

IWE ITỌSẸ OHUN GBOGBO
NINU ODU MẸRINDINLOGUN

Iwe yi kun fun Asọtẹlẹ ati wipe, yio din ọ lowo YẸMIWO" ku, nitoripe iwọ na yio le ma da ṣe AYẸWO fun ara rẹ
KOSEMANI" ni iwe na, 2/6d pere ni a nta:- Postage 9d
ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
8, Idumagbo Avenue
Lagos Nigeria (Leti Ọja Jankara)

## Iwe si Olotu Irohin Imọlẹ

# Ilu Aiyetoro Nfẹ Ile Iwosan Nla

Olotu Jọwọ gba mi ni aye diẹ ninu Iwe nyin to kun fun ọgbọn ati oye lati kesi Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lati ṣe iranlọwọ fun awa enia ilu Aiyetoro lọna bi a ti ṣe ni Ile Iwosan nla nibiti awọn enia ilu na yio ti ma lọ ṣe itọju ara wọn ati paapa lati le mu awọn alaiṣan dinku ninu ilu na.

Fun nkan bi ọdun diẹ ni a ti nkesi Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun lati kọ ile Iwosan yi fun wa ti eleyi jẹ ohun pataki to tọ ki Ijọbẹ Ipinlẹ na ati awon nkan miran bi ina monamona ati awon idagbasoke miran.

Inu awa enia ilu na yio dun bi Ijoba Ipinlẹ na ba fun wa ni awon nkan ti a nbere yi ni kiakia gẹgẹbi a ti nfẹ si.

Olotu mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi oko Ọba ko ni ṣa nyin lẹsẹ o, ajinde yio ma jẹ fun nyin o.

Emi ni
Laisu Baṣiru
AIYETORO.

Ti egbe olomi N P C ba tile nfi iya je wa ju bayi lo o daju pe awa ti a je egbe odo Afenifere ko nititori na lo di egbe Olomi atipe ohunti o ye ki a fi ti egbon wa Ọgbeni J S Ọlawoyin se apere fun ohunti egbe Olomi fi oju re ri ko titori na kuro ninu egbe Afẹnifẹre,

## A Dupẹ Lowo Ọgbẹni Balogun

OLOTU. Inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye ranpẹ ninu iwe ayin to kun fun ẹgbọn ati oye lati budẹ lọwọ Alaga ẹgbẹ OdọAfẹnifẹre ti Ile Igbomina ẹ ka Eko Ọgbeni J. K. Balogun nipa awon oro ti o fi ngba awon omo ile Igbomina nile ati lok o ko si gbagbe gbogbo oro ti Alaga ẹgbẹ odo Afẹnifẹre na ma fi nto wa leti nipa eto ipibo si Ile Igbimo Aṣofin Ijoba Ipinlẹ Ariwa to nbo yi.

Gẹgẹbi ohunti ogbẹni Balogun ti mo pe ko si egbe miran ni ile Igbomina ju egbe Afenifere lo ati pe titi ojo a ko iku se egbe miran ju egbe Afenifere lo.



Ọgbẹni Balogun

Emi ni
Lawal Ajiboye
EKO

BERE FUN OJULOWO EGBOGI—

## "Congreve's Iodo From—Oinment



Atamataṣe ni egbogi" ADIBLEGBO" yi j· fun itọju gbo gbo oriṣiriṣi "EGBO—ẸSẸ" ni kiakia bi o ti wu ki ọjọ rẹ ti le pẹ to, Adielegbo yi ko ni ẹgbẹ nipa wipe awa ko idọti ni bi ẹri gbogbo ti ba wa loja egbo patapata jade oju re yio si mo daradara .Lẹhinna oju egbo yi o ba jin sinu yio jeki oju re hu wa soke, yio si pọn daradara tun bakanna ko si mọ werewere ni yio si san patapata Alafia de si ọ niyen t—

Ri daju gbangba wipe awon sobu ti a da oruko won abssale iwe yi ni ogbe ranṣe lọ ra. Bibeko awon Elerọ ihii on ijibiti yio ta 'Adamodi' re fun o maṣe gba rarao

Waterloo Medicine Stores
8 PalmChurch Street Lagos
22878 Lagos Nigeria (Oja Ita Faaji)
UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street Lagos

## Ha Kini Eleyi




OGUN A PA YANMU—YANMU
OLORI ERIN MẸTA

Three Elephant Brand mosquito coils dara pupọ A ni O dara jus gbogbo ogun a pa yanmuyanmu yoku lọ,
O npa yanmuyanmu ninu ile ni kiakia orun rẹ si dara pupọ ju gbogbo ogun yanmuyanmu yoku lọ. Bakanna ni o si tun yara pa ayan ati idun,
Tete lọ ra packet ogun yanmuyanmu, Three Elephant brand coils tirẹ loni, ki o si danwo; iwọ y o ri bi o tiṣe pa gbogbo yanmuyanmu inu ile rẹ ti Iwọ ati awọn ọmọ rẹ 'yio si sun daradara
Ki o ri daju pe ogun yanmuyanmu orl erin mẹta ni awọn mu fun ọ
Three Elephant mosquito Brand coils yi wa ni ṣọbu lasitọja kakiri orilẹ ede yi

Distributor

AMOS GBENLE & BROTHERS
34: Docemọ Street Lagos.
6 & 11 Balogun Street West



# Okunrin Kan Fi Ẹwọn Oṣu Mejila Jura

IBADAN. Ni opin ọsẹ to kọja ni Adajọ ile ẹjọ kekere ti ilu Ibadan ti paṣẹ pe ki ọdaran ọkunrin kan Ọlatunji Oyekan ẹni odun mẹdogbọn yara lọ fi ẹwọn oṣu mejila jura lori ẹsun pe ọdaran na ba awọn nkan ẹgbọn rẹ ati iyawo ẹgbọn rẹ jẹ.

Ninu oro olopa to ba ọdaran na ṣe ẹjọ ni o ti se alaye fun Adajọ ile ejọ na pe odaran okunrin na fi agb ra s ilei un iyara ti iyawo egbon re ninu yara na eyiti o jẹ pe odaran na ti ba opolopo awon nkan iyawo egbon rẹ jẹ.

Gbogbo iye owo awon nkan ti odaran omokunrin na baje ti o si jẹ ti iyawo egbon re si jẹ ponun mẹrin lelogun ati sile marun ni adugbo Aremọ Street Ibadan ni ojo keje oṣu keji odun to koja lo yi

Ọlopa to ba odaran na ṣe ejo Ọgbeni Daniel Ojo tun fi ye ile ejo na pe nigbati isele na sele, o ni odaran na si ti mu emu yo eyiti ko si mo ohun ti on nse mo.

Ọdaran omo okunrin na Olatunji Oyekan si fi ye ile ejo pe on gba wipe on jebi esun na ati pe emu ti on mu lo si fa eleyi ti on ko si mo ohun tị on ṣe mo

Odaran na tun se alaye pe ohun ti o tun bi on ninu pupo ni iwa kan ti egbon on ho nipa pe o gbe mat-r si eyiti o fi n un pada fun iyawo eyiti o je pe on na lo fi ta iyawo re lore.

Ọkunrin na s ro ile ejo pe ki o ni oju anu rẹ si on ati pe ki o jowo mase gbe on si ewon.

Ninu idajo Adajo ile ejo na ni o ti se alaye pe ki odaran omo kunrin na yara lo fi ewon osu mejila jura.

Ninu ile ejo kanna ni omo kunrin kan Emmanuel Kilanko ti o se alaye pe on sise ni ile ise minista alamojuto eto ogbin fun ijoba Ipinlẹ Iwo Orun Naijiria ni o ti se alaye pe on ko jebi pe awon ol pa ka taba igbo mo on lowo Adajo na si gba iduro omo kunrin na ni ogorun ponun ati enia kan ti yio duro fun ile ejo na ti s u n gbigbo ejo na si ojo ketala osu to mbo.

## YE IRAWO RE WO

AQUARIUS (Jan 22 Feb 20) Lọ fi ara lele, ki o si ti ọkan si oro ariri ara rẹ, nitori ire ṣi mbẹ pẹlu re nibẹ

PISCES (Feb 21 May 20) Iwọ yio ni ilọsiwaju gidigidi pẹlupẹlu arẹ ti o fẹ yọ ọ lẹnu, Enikan yo ton ṣe ile ri fun o wipe ifẹ rẹ si mbe ni ọkan en.

ARIES (May 21 April 20) Ayọ ni iwọ yio fi bẹrẹ ohun kan loni ṣugbọn nigbati o ba y isan yio de s ọ inu yio si ma bi ọ lẹnu nkan re ti o baiemaṣe banu je adawodiẹni

TAURUS (April 21 May 20) Ni ba ọjọ ti o wa fun ọ yi, Iwọ yio ni agbara lati le yanju awọn iṣoro to wa fun ọ ara rẹ yio si ya ko si ija lari iwọ pẹlu awọn ọrẹ rẹ, ilosiwaju wa fun ọ jojo

GEMENI (May 21 June 21) Lẹhinti ara rẹ gbọn diẹ fi ara mọ awon ọrẹ rẹ, ki o si kuro lọdo awọn enia kan

CANCER (June 22 July 22) Iṣoro kan ti o ferasin yio ma ṣe o ni ṣiba ṣibo, o yẹ ki o ri gbangba bi nkan ti ri iwo yio si ri daju wipe ninu yotomi ni iwọ wa,

LEO (July 23 Aug 22) Yanju gbogbo isoro rẹ kuro Ki ọsan to pọn lẹhin na dubulẹ ki esan diẹ ki o wa gba tegun lọ pelu awọn ore rẹ

VIRGO (Aug 23 Sept 23) Ibinu ti o baji ni owuro yi nkan bere si ni dada bi osi ti npon, dupe fun enikan ti o ba pade ati irohin ayo kan ti o gbo, ti o mu ki inu re ma dun

LIBRA (Sept 24 Oct 23) Gbokegbodo yio po fun o ni akoko ṣugbon gbogbo re yio je ire fun o ṣugbọn nitori ohun kan ti a ko sile jeki inu baje mase binu pupo iwo yio ri ire laipe

SCORPIO (Oct 24 Nov 22) Lo akoko faaji re pelu awon elufe re to le ti o lo se abewo awon enia awon elo miran yio fe lati gbo oro lenu re oro owo kan yio dija sile

SAGITTARIUS (Nov 23 Dec 21) Ko si isoro kan ni osa re ti o se pataki loni sugbon ki o lo dubule ki o sun tabi ki o lo mu faaji pelu awon ore re

CAPRICORN (Dec 22 Jan 21) Ojo oni le koko bi oju eja o ye ki o din ise re ku die ki o si ma se anu fun awon enia


GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ATI OGO NIPA DYNAMIREN TONIKI

ALE-IBI-ALE Egbogi Tọ ki amọnu, titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ Agbara ati Ajẹbidan ṣẹ lara agbalagba Ọkunrin ati Obinrin gbogbo

Bi arẹ ara ba nmu ọ, ni gbakugba fun wahala tabi iṣẹ ṣiṣe ti o ko le jẹun dara dara, tabi ki o male sun dada de ọkan lọsan tabi awọn ṣan ara rẹ gbogbo ki ṣe fun daradara ti Emi Breath inu ko ba kunlẹ daradara wọn iṣẹ tabi wahala sise tabi inu awọn ailera gbogbo nyin ti ọjọ ori (age) ba ti kọja ogbọn ọdun si adọrin tabi jubẹ lọ mọ daju pe DYNAMIREN ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara rẹ di ọtun pata oju rẹ yio si walẹ re kete alafia ati Igbadun de Bere Dynamiren yi ni ọọbu awọn :-



Waterloo Medecine Stores
8. Palm Church Street P. O Box 333 Lagos

NIGERIAN MEDICINE STORES
Tinubu Square Lagos

LAGOS ISLAND CHEMIST
Nnamdi Azikiwe Street, Lagos

UNITED DRUG CHEMIST
Alli Street, Lagos.

ADEDUN CHEMIT
14, Wakeman Street

ATI NI ṢỌBU
IJẸBU OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA IBADAN


## Ẹ maa Ka Iwe Irohin Imọlẹ

# Ọmọ Ọlọrun Ni Jesu

## Lati Oju Ewe Keji

kejidinlogun titi de kejilelogun O tun so pe bi ibi Jesu Kristi ti ri niyi Ni ako ko ti a fe Maria iya re fun Josefu ki awon to pade.

Ki e tun lo wo Luku ori kini ese kerindinlogbon titi de ese kerindinlogoji eyiti o so pe Ni osu kefa a ran Angeli Gabriel l a t i odo Ọlọrun lo si ilu kan ni Galili ti a npe ni Nasareti

Ẹnyin ara mi ninu Oluwa mo ro pe oti ye nyin daada wipe ọmọ Ọlọrun ni Jesu Kristi ise Mo fe so fun nyin ni ibere oro mi pe lehinti Bibeli so asotele nipa Jesu Kristi be ni kurani tun jeri si pe otitọ ni ki e lo wo inu kurani Surat kokandin logun ayat kerindinlogun titi de kejilelogun

Ẹ tun lo wo Sura kokan lelogun Ayat kerindinlo gbọn Surat kerindinladorin Ayat kejila ati beebe lọ Nitorina mo fe ki e lo wo yika gbogbo aiye wipe ọmọ bibi inu Ọlọrun ni Jesu Kristi ise

Ni ipari oro mi mo be nyin enyin Musulumi pe ki e ma binu pupo ati pe ki e tun la mo daju wipe Jesu Kristi nikan ni onișe nla ninu gbogbo awon Anabi on nikan ni olugbala ara aiye pelu

Bi o ba tun di igba mi ran emi yio ma so bi Jesu Kristi ti se je onise nla ati bi o ti se je olugbala fun gbogbo aiye

Mo tun ro enyin ti o fe ma fi oro se iyan jije lati lo mo daju pe otito ni Jesu je ọmọ Ọlọrun nitorina oro esin ko ie di ija larin enyin onigbagbo ati enyin musulumi bakanna nitoripe Ọlọrun kanna ni ajijo nsin

Olotu e se pupo e ku ise Ọlọrun yio si ma wa , elu nyin ati awon isongbe nyin pelu e ko ni si oro na tẹ o

# Iwe Itaja 1966

Idamu owo ha wa fun ọ bi
Abiku ha nyọ ọ lẹnu bi
Airi iṣẹ se ha wa fun ọ bi
Ailern mba ọ ja bi **?**

Iwọ le bọ ninu gbogbo wahala aiye wonyi ti iwọ ba ra ninu awọn ohun Ijinlẹ Iṣẹdalẹ Yoruba ti a to leṣẹṣẹ si isalẹ yi.

1 Iwe Egbogi Ajẹbidan 25/— di 22/6
2 Iwe Afọsẹ Iṣẹdalẹ Yoruba ati Psalm Ajẹbidan 4/6 di 3/6
3 Iwe Itumọ Ala ati Ogun Wibẹjẹbẹ 4/6 di 3/6
4 Iwe Egbogi Awogba Arun 20/— di 17/6
5 Iwe Ilana Ifa Yanrin tirẹ ati etutu șișe 20/- di 17/6
6 Gbedegbẹyọ Hausa 3/—
7 Iwe Aniyan Irun 2/— di 1/—
8 Turari Iṣegun Ajẹ ati Itaja 10/6 Pangolo 2/6 paket

Fi Owo ranșe si
J, O, SHOYINKA
P, O, Box 159
MUSHIN
tabi
9, Iyala Street Oduabọrẹ, Mushin

a successful future
means planning **Now!**
Have you planned for the security of your family's future? Start a programme of Life Insurance NOW with
**GREAT NIGERIA INSURANCE Co. Ltd.,**
INCORPORATED IN NIGERIA
Enquire now for full details of our low cost endowment policy.
HEAD OFFICE:
39/41 MARTINS STREET,
P.O. Box 2314, LAGOS
TELEPHONE 28381.
BRANCHES AND AGENTS THROUGHOUT NIGERIA.

**The NEW HOOVER**
Washing Machine
Makes Clothes
Whiter and Brighter
It's easier the....
**HOOVER** way

The NEW HOOVERMATIC washes rinses spins dry 5lbs. of clothes in 8 minutes all in one continuous operation. That's the amazing performance of the new Hoovermatic a combined Washing Machine and Spin Dryer



AVAILABLE AT
LEVENTIS TECHNICAL
MARINA - IDDO - IBADAN -
KADUNA - JOS - KANO -
P. HARCOURT - ABA
and Kingsway Stores

# KERE O

Nje o ti ni ninu "IWE ITAN ODUDUWA tose ṣẹjade ?

Ha ! Kosemani ni iwe na jẹ fun ọmọ Yoruba Iwe na kun fun itan iṣẹdalẹ Yoruba, Kedere ni aworan Oduduwa ati ti ọmọ rẹ han ninu rẹ.

Maṣe jẹki owọn rohin itan ilu rẹ fun ọ 3/- pere ni. Postage 9d

Tete fowo tirẹ ranṣẹ si:-
ẸSAN KOGBOGUN SERVICE
8 Idumagbo Avenue Lagos Nigeria

# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE TẸNI GBOGBO LAWA

NO 1,670 THURSDAY, FEBRUARY 17 1966 (2D)


## Awon Omo Unifasiti Binu Ko Onjẹ Silẹ

IBADAN:— Ni ọjọ Isẹgun ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu yi ni gbogbo awọn ọmọ Ile ẹkọ nla Unifasiti Ibadan binu ti gbogbo wọn si kọ onjẹ wọn silẹ ti nwọn ko si jẹ onjẹ wọn.

Irohin fi ye wa pe, o le ni ẹdẹgbẹta [500] awọn ọmọ Unifasiti na ti nwọn binu kọ onjẹ wọn silẹ ti nwọn ko jẹun ni ọjọ na.

Agbọrọsọ awọn akẹkọ na ṣe alaye fun Oniwe Irohin wa pe, lati igbati awọn ti bẹrẹ ile ẹkọ awọn ninu ọdun yi, onjẹ ti awọn ti nṣe onjẹ na nṣe fun awọn ko dara fun ọmọ eranko lati jẹ, ti a ko tun wa gbọdọ sọ wipe ọmọ enia mọ.

O tun sọ siwaju ninu ọrọ rẹ pe ọpọlọpọ ni awọn ọmọ ti nwọn ti gbe lọ si Ile Iwosan lori onjẹ ti ko dara ti wọn nfun awọn jẹ ninu Ile ẹkọ na.

Ṣugbọn nigbati awọn so fun wọn ti nwọn ko si yi onjẹ na pada ni gbogbo awọn ba ti ṣe binu ti awọn si kọ onjẹ onjẹ na silẹ. O tilẹ tun sọ pẹlu pe ki Oniwe Irohin wa ba on kalọ ki o lọ tọ onjẹ na wo.

Ṣugbọn ọjọgbọn Kenneth Dike ti iṣe Alaga Ile ẹkọ Unifasiti na sọ fun Oniwe Irohin wa nigbati o bere oro na wipe on yio risi oro awon omo na kiakia.

# ỌMỌ BINRIN KAN KU SINU INA

UGEP:— Gbẹgẹdẹgbina ni abuleko kan ti nwọn npe ni Adini ẹkun Ugep Ipinlẹ ila Orun Naijiria nigbati ina nla kan ṣẹlẹ ni ilu na eyiti ọlọmọ bẹrẹsi gbe ọmọ ti igba ti ina nla na ṣẹlẹ eyiti ọmọ binrin kan ti o jẹ ọmọ ọdun marun ku sinu ina to ṣẹlẹ ni ilu na ti ọpọlọpọ dukia si jona sinu ina na ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹrinla oṣu yi.

Ninu ijamba ina nla to ṣẹlẹ ni abuleko na ni igba ile si jona raurau sinu ina nla ti awọn dukia bi Basikulu eyiti gbogbo rẹ jẹ ọgọfa, apo irẹsi, apo iṣu ati awọn ohun jijẹ miran si jona raurau sinu ina nla to ṣẹlẹ bakanna ni irinsẹ awọn Ẹlọ (Machine) eyiti gbogbo rẹ jẹ marundinlagọrun si tun jon patapata sinu ina nla to ṣẹlẹ ni ilu na.

Irohin fi ye wa pe nṣe ni ọmọ binrin na sun nigbati ijamba ina na ṣẹlẹ eyiti o jẹ pe oju Orun ni ina na ti ba ọmọ binrin kekere ti o si jo ku sinu ina,

Ọpọlọpọ awọn enia abuleko na lo si fi ara gbọgbẹ ninu ina na nigbati awọn enia na ngbero lati ri aye ko awọn ẹru to wa ninu awọn ile wọn jade eyiti pe ina si ti wọ inu awọn ile na.

Irohin lati ọdọ awọn Ọlọpa fi ye wa pe nwọn ko ti mọ iru ohunti o ṣẹlẹ si ina nla na ati pe nṣe ni awọn Ọlọpa si nṣe iwadi ohunti o fa ijamba ina nla na wa.

Oniwe Irohin wa to lọ sibi ti iṣẹlẹ na ti ṣẹlẹ fi ye wa pe nwọn ti gbe oku ọmọ binrin to jo ku sinu ina na lọ si Ile Iwosan ti Ilu Obubra lati lọ ṣe ayẹwo rẹ ninu Ile Iwosan lakulaku.

Ninu irohin ti o tun de Ile Iṣẹ wa ni ọsan ọjọ ọjọ Ru ti iṣe ọjọ kẹrindinlogun oṣu yi tun fi ye wa pe awọn Ọlọpa ri oku ọmọ kunrin kan ti nwọn ko mọ oruko rẹ tabi ibiti o ti wa ni gbangba ode ile ẹjọ giga ti ilu Onitsha.

Irohin fi ye wa pe nṣe ni ọkunrin ti awọn Ọlọpa ri oku rẹ na nbọ lati ibiti o ti lọ ba won ṣe ayẹyẹ inawo kan ti o si nfẹ pada si ile rẹ eyiti ọkunrin na si ku si gbangba ode ile ẹjọ giga na.

Irohin lati ọwọ awọn Ọlọpa ti ilu Onitsha fi ye wa nwọn ti bẹrẹsi ṣe iwadi ohuntio pa ọkunrin na.

Awọn Ọlọpa ko mu enikankan to pa ọkunrin ti awọn Ọlọpa ri oku rẹ gbe ati pe nwọn ti gbe oku ọkunrin na lọ si ile iwosan ti awọn lakulaku ti ilu Onitsha lati lọ ṣe ayẹwo rẹ bayi.

Bakanna ni irohin tun fi ye wa lati ilu Onitsha pe ọkunrin Onisowo kan ni ilu Kano jabọ ninu mọto ati pe lẹsẹkẹsẹ na ni okunrin na ti nwọn ni Christopher ku nigbati o jabọ ninu moto akero na.

Irohin awọn Ọlọpa tun fi ye wa pe Ọgbẹni Christopher joko le tente mọto akero na eyiti o fi jabọ lati tente mọto na ti o si ku lẹsẹkẹsẹ.

## Balewa

Lati Oju Ewe Kini

binrin titun na Zainabu.

Irohin fi ye wa pe ọpọlọpọ ninu awọn enia jankanjankan ni Ipinlẹ Ariwa ilẹ Naijiria lo pesẹ si bi ayẹyẹ isọmọ titun na loruko.

# Nwọn Dana Sun Ọlọpa

## Lati Oju Ewe Kini

nwọn sọ pe ko ju ọmọ ọdun mẹwa lo ba sare lo gbe epo mọto ti o si dan si ọlọpa na lara nibiti o gbe sun nile si ti o si tun ṣaon si ọlọpa na.

Were, oro di bo duro o gbe, ni gbogbo awọn omo ile ẹk - na ba tuka yanga mo Ọlọpa na lori, nigbati awon Ọlọpa miran yio fi sare de lati Tesan, Ọlọpa na ti jona rau-rau, oku rẹ ni nwọn si gbe nile lo si Ile Iwosan lakulaku fun ayẹwo awon Dokita.

# Ijoba Ibilẹ Ogbomosho

LATI OJU EWE KINI

enia kankan ki ba ti mọ ohunti akọwe Ile Igbimọ Ijọba Ibilẹ na wa sọ yi

Agbọrọsọ na tun sọ fun Oniwe Irohin wa siwaju wipe, bi ọrọ ti on nsọ yi ko ba ri bẹẹ kini ṣe ti ako wena ko ti so fun gbogbo aiye gbo ki o to di asiko yi

O tun sọ pẹlu wipe, ko si ẹniti o gbọ ninu gbogbo awọn ọmọ Ile Igbimọ na siwaju asiko yi, bi ko si si ohunti o delẹ yi, boya awọn ki ba ti gbọ ohunkohun nipa ọrọ na pẹlu.

Ọgbẹni Oke wa kesi gbo gbo awọn ara ilu wipe, ki nwọn tete yara wa san Owo—Ori wọn, ki Ijọba le ba tete san gbogbo gbese ti o wa ni ọrun wọn kiakia laisi idaduro kankan fun won.

O tun so pẹlu wipe, bi Ijoba ba san gbogbo gbese na tan nigbati awon enia ba ti san owo ori won, eleyi yio tun mu ki Ijoba tun le ṣe gbogbo awon iṣẹ ti o wa niwaju won, lati ṣe fun idagbasoke ati ilosiwaju gbogbo awon enia ti nwon ngbe inu ilu na lasiko.

Ki ipade ọjọ na to pari, Oloye Bajomo, ẹniti iṣe Ajẹle agbegbe Ogbomosho tun rọ awọn Ọba ati Ijoye lati tete kosi awọn enia won ki nwon le tete san Owo—Ori lasiko.


Printed and Published By Modupe Printing Press, ... Street, Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADBOSUN 25 Branco Street Lagos 17/2/66